ELETI OFE

'A-NJU-WON KO SE WI LEJO'

VOL XIV NO 935 LAGOS SATURDAY AUGUST 22 - AUGUST 28 1964 KOBO MEJI (2D)

**Eleyi Ara!**

# Iya Onigbagbo Ku Sori Aga Adura

PỌTA (PORT-HARCOURT — Eleyi ara! (ışirişi nkan ni o nşẹlẹ ninu aiye ti a wa nisisiyi, bi nkan ki a lẹ si Mọsalasi ki a lọ kirun, ki a pada dele ki a doku. Irohin a gbọ yanu kan ti a gbọ ni ọsan ana ni ti iya onigbagbọ kan, Regina Iyalla ti o lọ gbadura ninu Ṣọọşi kan ni Diobu ti o si ku bamubamu sibẹ.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ lati ẹdọ onirohin wa, nwọn ni nkankan ko şe obinrin na, ara rẹ si le bi akẹ-kọun, ki o to fi ile rẹ silẹ lọ si Ṣọọşi na fun adura owurọ ti awọn onigbagbọ ma ngba.

Nwọn ni lẹhinti alufa ile adura na ka ọrọ ninu bayibulu tan, ti gbogbo awọn ijọ si kunle fun adura ọ gbọ, ni awọn ti obinrin na jokoti ni Ṣọọşi na şe akiyesi wipe o to di de titi, nwọn şebi o sun lọ ni afi igbati nwọn ji i titi ti ko ji ni awọn ijọ ba tuka. Awọn ọlọpa ti gbe oku obinrin na lọ si ile lakulaku.

## Awon Egbe Meri Da Egbe Ajumosepo Sile Ni Kaduna

IBADAN — A ri irohin kan gbọ lati Ibadan ni ọjọ egun oşu yi pe Olo e Akintọla ti pada de si Ibadan lati Kaduna lẹhin ipade alaıçnrẹn kan ti o lọ şe nibẹ nigbati o ti gunlẹ pelu ọkọ ofurufu ni Ibadan tan, o sọfun awọn oniwe irohin pe ip de awọn ẹgbẹ NPC, NNDP, MDF ati NDC ti pinnu dida ẹgbẹ oşelu ajumọşe kan silẹ eyiti orukọ rẹ yio ma jẹ 'Ẹgbẹ Ilu Parapọ ti lẹ Naijiria.

Oloye Akintọla ni idi ti nwọn fi da ẹgbẹ yi silẹ ni lati mu ki irẹpọ wa larin awọn ara ilẹ Naijiria ati iduro şinşin fun ilu ijọba adaşe wa ki ọgikaluku to wa ni ilu le jẹ anfani rẹ, a ti i pe ajọşe ẹgbẹ na yio dibo lori gbo gbo ijoko ninu ile igbimọ ijọba aşofin, awọn yio si ja fitafita gẹgẹbi agbo kanşoşo ninu idibo to nbọ.

Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Adajo Gb'awon Alarede Loro Ni Kotu Ikeja

IKẸJA — Ni ọjọ erinla oşu yi, adajọ kootu gauran kan ni Ikeja, Ọgbẹni Moses Oyemade sọrọ imọran kan pe awọn a ẹ ọ ọmọ ilẹ Naijiria ti nwọn nfẹyawo alarede nilu Oyinbo ni lati pada wale lati şe ibẹwo ara wọn fun bi oşu mẹfa ki nwọn ba to pe nwọn gbeyawo nitoripe ọrọ a ngbe iyawo alarede o nşe n an ekere rara., eyi ni o si nje ki awọn a ọkọ ọmọ wa pọ nilu.

Imọran yi ni adajọ Oyemade da nigbati o nfọwọsi iwe ẹbẹ wipe ki nwọn tu awọn alarede kan ka ti nwọn gbe wa siwaju rẹ lati ọwọ ọ ọ ati iyawo an ti nwọn ti fẹ ara wọn fun ibi ọdun mẹrin sẹhin ni ilu Oyinbo Ọgbẹni Folorunsho Akinsọla, onişe ẹrọ omi, ati iyawo rẹ, Adenike Akinsọla, ẹniti o ti nşe akọwe ni ile ẹ ọ ti nwọn şẹşẹ dasilẹ ni Eko.

Adajọ ni gbogbo igbeyawo to ba jẹ eyiti nwọn ba şe ni oke o un ajabi ni ilu Oyinbo ni ki isaba yọri si rere nigbati ọkọ ati iyawo ba pada dele tan. Ọgbẹni Akinsọla fi iwe ẹbẹ yi siwaju adajọ lati tu igbeyawo wọn ka nitoripe iyawo on ni inu buru u o, si nyan ale mọ on lara.

(Wo iyo u loju ewe keji)

## Adajo So Adajo

YABA—Nkan kan ni kotu awọn Ọlọpa Yaba nigbati Ọgbẹni F Ogunmuyiwa, adajọ ẹgba fun awọn Ọlọpa sọ ọkunrin kan, Daniel Bayọ Gomez ti o npe ara rẹ ni adajọ kiri sẹwọn ọdun kan ati abọ. Awọn Ọlọpa ni arufin Gomez yi fi adajọ ti o npe ara rẹ yi lu jibiti pupọ ki ọwọ awọn ọlọpa to tẹ ẹ.

Nwọn ni pọnun mẹdọgbọn o din şile mẹrin ni o fi jibiti gba lọwọ ọkunrin kan, ti o jẹ Samuel Afiogun ti o nşe işẹ agbawo ni

## Aburadi Sewon

kan Ẹsun ẹfa ni awọn ọlọpa ka si lẹ ẹ arufin yi ... wipe on jibiti ri ọkan şoşo o ... ki nwọn gbe awọn marun to ku ti awọn ọlọpa mu on ... wipe on gba pọnu mẹrinlelogun ati şile mẹrindinlogun lọwọ Samuel Afiogun,

Awọn Ọlọpa ni Gomez pa gba owo lowo Afiogun wipe on yio ba ipo on gẹgẹbi adajọ ... ba a wa şẹ ibi kan l'Eko.

(Wo iyoku loju ewe keji)

# Adajọ So Adajọ Aburadi S'ewon

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Nigbati adajọ ma wi, o ni ẹsun nipa fifi ara ẹni we adajọ jẹ ohun to le pupọ fun kotu ṣe idajọ lori rẹ gẹgẹbi itọsẹ ofin ti nwọn fi mu arufin yi wa si iwaju on nitoripe ti o ṣe iṣẹ kan to jẹ mọ iṣẹ adajọ ni Gomez iba jẹbi, ti o ba tun jẹ wipe o lọ si ile ọti yen lati ṣe iṣẹkiṣẹ kan to jẹ mọ ti adajọ ni nkan miran ni a ba ma wi.

Ọ g b ẹ n i Ogunmuyiwa tun fi ye ni pe ni arufin yi ko ti ṣe nkankan to jẹ iṣẹ akọwe kotu fun ibura tabi ki o tilẹ joko ninu kotu kankan bi adajọ.

Lẹhin eyi, adajọ foju iuu wo gbogbo iwa ofiu to wa lọdọ rẹ lati wadi eyiti o mu u, ṣugbọn ko ri i, nigbana ni Gomez paapa wa jẹwọ ẹṣẹ na.

Larin igba kan ninu gbigbọ ẹjọ yi, o dabi ẹnipe Gomez yio bọ ninu ẹjọ na nitoripe ko si ofin to ba ẹsun ti nwọn mu fun lọ, segbọn adajọ ni on yio ju sẹwọn ati pe o le pe ẹjọ kotẹmilọrun to ba fẹ nitoripe kọkọrọ ilana ofin to fuu on ni aṣẹ wa lọwọ on.

Nigbati ẹjọ na kọkọ bẹrẹ adajọ ti ṣe ppejuwe Gomez gẹgẹbi onijibiti ati ẹniakenia, ati Ọgbẹni Akọgun bi gọng4ṣu kau ko tilẹ ni ifura rara titi Gomez fi gbowo lọwọ rẹ ui igba marun leralera.

## Adajọ Gb'awon Alarede Loro Ni Kotu Ikeja

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Nigbati adajọ ti gba pe ki nwọn kọ ara wọn tan, o ni dajudaju gẹgẹbi ẹjọ to wa niwaju on, o fi han pẹ otitọ ni obinrin na j ẹ b i panṣaga ti o ṣe pẹlu ọkunrin kan, adajọ niki ale rẹ na, Ọgbẹni A.O. Louis ẹni ti nwọn darukọ sinu iwe iyẹjọ lọ san pọnuu mẹdogun fun ọkọ alarede Adenaikẹ, Ọgbẹni Akinsọla

Lẹhinna adajọ wa ni k Ọgbẹni Akinsọla ma fun iyawo rẹ ni pọnun meta meta loṣuṣu fun itọju ọmọ ọdun meji ti iyawo alarede ntọ lọwọ.

Nigbati ẹjọ yi kọkọ bẹrẹ, Akinshọla sọ ni kotu pe awọn fẹ ara wọn ni London ni ọdun 1960, ati pe ko pe lẹhin igbeyawo yi, igbakugba ni ija ma nṣẹlẹ ninu ile nitoripe ojojumọ ni Adenikẹ ma nlọ sode pẹlu awọn ọkunrin miran nigbati on ba wa lẹnu iṣẹ

# Iyawo Akintola Kede Egbe Demo

IBADAN—Nị igba kan rị a gbọ pe obinrịn ko le fi iga gbaga rọ pẹlu ọkunrin, ṣugbọn ni aịye isisiyi ko ri bẹ mọ, iru apẹrẹ yị ni a ri ninu iṣe ribịribị ti Iyaafịn pataki kan nṣe ni ilu Ibadan lẹnu lọọlọ yi eyịtị ẹyin onkawe wa yio ri ka ninu itọsẹ iwe wa yi.



**Oloye Samuel Ladoke Akintola**

OLORI ẸGBẸ DẸMỌ

Gẹgẹbị a ti mọ pe ti akoko idịbo ba nsunmọ etile, onikalku awọn Olotu iyawo ati awọn ọmọ ẹgbẹ wọn ni nwọn nṣe ịkede idibo kakiri lati le jagunmolu kị nwọn ba le tun yan wọn si aye awọn oṣelu.

...lati bi ọsẹ mẹta ni iyawo Oloye Akintola, Iyaafin Faderera Akintọla iyawo Olotu ipinlẹ Iwọ Orun ati aṣiwaju ẹgbẹ Dẹmọ fun ẹka ti awọn obinrin ti bẹrẹsi ṣe ikede idịbo ati ẹgbẹ kakịri agbegbe Iwọ Orun fun awọn obinrịn!

...O ni ki nwọn parapọ pẹlu ẹgunlọgọ awọn miran ninu ẹgbẹ ọkọ on (Dẹmọ) lati ṣe alekun aafani ati ilọsiwaju ninu ilu wọn.

## Ijagboro Awon Obinrin Ijebu-Ode Pari

IJẸBU-ODE — Nị ọjọ kẹrinla oṣu yi ni a gbọ irohịn lati ịjẹbu Ode wipe awọn obinrin ọlọja ti nwọn kọ lati taja ni Ijẹbu- Ode lori aṣẹ kan ti igbimọ awọn afunịsọ Kansulu Ijẹbu Ode ṣe nipa gbigba isọ lọja ti pari ọrọ wọn.

Awọn obinrịn na ti kọkọ so panpa pọ, nwọn si ṣe iṣọugbọn lorị aṣẹ ti kansulu pa pe kị nwọn ma lẹ aworan ara wọn mọ iwe ibere fun iṣọ lọja lati ru ilu pada bọ wọn si jẹ nkan ti o tị jẹ ịp de kan ti oloti wọn ṣe pẹlu Ọba Awujalẹ ti Ijẹbu Ode Ọba S.K.ru Adetọna ati awọn ijoye rẹ to wa ninu agbala Ọba

Ipade na jẹ eyiti nwọn ṣe ninu iyẹwu ti ẹnikẹni ko ri, o si gba to wakati kan, bẹẹ ko si si ọkan ninu awọn aṣoju Kansulu o bẹ, Ọba Adetọna bẹ wọn pe ki nwọn pada sẹ u ọja tita wọn ki o ma ba si ehị ati aba ẹ ọkan larin ilu.

Ọba Awujalẹ tun ṣeleri fun awọn obịnrin na wipe on yio ta awọn ọmọ ẹgbẹ Kansulu sọrọ lori ero ati pari ọrọ na, gbogbo awọn ọlọmọlanke ati awọn ẹlẹran ni nwọn si ti pada sinu iṣẹ wọn.

# Egbe Olomi Fe Gba Gbogbo Ijoko Igbimo L'Eko

EKO— Ni ọjọ Ẹti ninu ọsẹ to kọja ni awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi ni awọn yio dibo fun gbogbo ijoko ninu ile igbimọ aṣofi ijọba ni ilu Eko ninu ibo to mbọ yi, nigbati Ọgbẹni B.C. Onyiuke to jẹ akọwe olupolowo ẹgbẹ yi ni Eko nsọrọ ni ọjọ Ẹti to kọja, o ni awọn ni yio bori ninu ibo to mbọ na.

Ọgbẹni Onyiuke fi awọn ẹgbẹ Alakukọ ati ti Ọlọpẹ suu fun ifọnnu lori orişiriṣi ileri ti ko lopin ati eyiti ko lẹsẹ nilẹ ti nwọn ma nṣe lati mu inira ba ibo didi, o tun sọpe iṣesi wọn ti o ti ni ifanimọra tẹlẹri ti di yẹpẹrẹ nisisiyi.

Siwaju sii, o ni ede aiyede to ti wa tẹlẹ ri larin awọn Oloye inu ẹgbẹ on ni Eko ni nwọn ti pari, ati pe ninu ipade gbogbogboo ti ẹgbẹ na ṣe laipẹ yi, nwọn yan Alhaji A. Laguda gẹgẹbi alaga ẹka ẹgbẹ Olomi ni Eko ṣugbọn lati igba na wa ni ko ti wa si ipade ẹgbẹ na mọ bi alaga.

Ọgbẹni Onyiuke ni ẹniti o tun jẹ aşiwaju ẹgbẹ na. Alhaji Yusnfu Maitama Sule, ti kọ iwe kan si Alhaji Ọkin lati d'ẹkun pipolowo ara rẹ kiri gẹgẹbi alaga.

# Adajo Kotu Ibile Ni Loya Agbaje Da Kotu On Ru

IBADAN — Oloye A.M.F. Agbaje, alaga igbimọ aṣofin ẹgbẹ Alakukọ ati ọmọ ẹgbẹ ile igbimọ awọn Ọba ni ipinlẹ Iwọ Orun ni a gbọ pe awọn ibilẹ ni Yemetu, Adeọyọ ni Ibadan mu ni ọjọ kẹtala oşu yi wipe ki o ma fara rẹ han awọn lojojumọ titi ti awọn yio fi mọ nkan ti awọn yio ṣe nipa ọrọ rẹ.

Ohun ti a gbọ pe nwọn mu fun ni ẹsun şişe ajojudi si kotu ati hihu iwẹ lọna ti o le ba alafia ilu fẹ ti awọn ọlọpa ni o ṣe ni kotu ibilẹ kan ni Akinyẹle. Awọn ọlọpa ni ki o duro fun ara rẹ.

Adajọ Akinyẹle ti o nṣe ni abule na to jẹ adajọ ni kotu ibilẹ abule na ni o ọrọ na sun awọn ọlọpa, adajọ yi funrara rẹ si tun lọ si ọfisi nla ti awọn ọlọpa ibilẹ to wa ni Yemẹtu ni owurọ na, o si sọ pe Lọya Agbaje da kotu on ru nigbati o wa si kotu na pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ.

O ni awọn kan pẹlu ada to nkọ yẹri lọwọ wọn wọ inu ayika kotu lọ lori eyiti on ati awọn miran salọ fun asala ẹmi awọn, nigbati Oloye Agbaje fesi si ẹsun na o ni idi ti on fi wa si kotu lọjọ na ni lati mu ẹbẹ kan wa siwaju kotu nitori awọn ọmọ ẹgbọ on ti adajọ Akyinyẹle ti o nda ẹjọ ni kotu na sọ sẹwọn, on ko si ba adajọ na lori ijo o rara.

Oloye Agbaje ni on si lọ si ọfisi awọn ọlọpa ni owurọ ọjọ na lọ sọfun wọn mf mu ti ọwọn ọlọpa nmu awọn ọmọ ẹgbẹ on pẹlu ikorira ọkan ni ileto Moniya lori ọrọ iwe owo ori wọn ti nwọn ni nwọn ko fi bẹ nwọn si ti gba owo-ori nkan bi ọdun mẹfa sẹhin.

A gbọ wipe lori ẹsun ti adajọ ibilẹ yi lọ fi Lọya Agbaje sun awọn ọlọpa wipe o di on lọwọ lẹnu iṣẹ on ninu kotu nigbati on nṣe ẹjọ lọwọ, agbẹ kan ti o ngbe abule Akinyẹle na ti orukọ rẹ njẹ Arasi Adisa ti lọ fi iwe bura ni iwaju awọn ọga ọga ọlọpa ibilẹ wipe oju on gbogbo ọrọ na şe, nigbati Lọya Agbaje wọ inu Kotu abule Akinyele o si adajọ kan lori aga rara lọjọ na.

Adisa ni on ni awọn ọlọpa ati a ọda mu fun owo-ori ni abule kan ni

(Wo yo ọ lo u ew ẹrin)

# E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

# ELETI—OFE

## ti o kun fun irohin aladun losose.

# NI IRANTI



A şe ikede yi ni iranti baba wa ọwọn, Oiogbe

**Alhaji Abdul Kareem Cole**

ẹniti o jẹ Oluwa ni ipe ni Ọjọ kejidinlogun Oşu August ninu ọdun 1958 l'Eko.
O di ọdun kẹfa ninu ọsẹ yi.

INA LILAI, WA INA ILEHI RAJIUNA.

ADUKE BENSON
Fun awọn ọmọ Oiogbe na

# ELETI - OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LEJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
38, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO 935 SATURDAY Aug. 22 – Aug 28 1964


## Oro Olotu:

# Awon Omo Egbe Omolofin Nse Bebe

Awọn Yoruba ni nwọn ma nsọ ọrọ kan wipe yinni yinni ki ẹni le ṣe miran; iru ọrọ ọlọgbọn awọn baba wa yi ni awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ yio fi yin awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọfin, ẹgbẹ ti nwọn da silẹ laipẹ yi ti nwọn si ti pa idan meje ti ọdẹ npa larin awọn ijoye ati awọn Ọba ilẹ Yoruba.

Nkan kini ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ti o jọ wa loju ni ija nla ti o bẹ silẹ larin Alaiyeluwa Aderẹmi Keji, Ọba Ọni Ile Ifẹ pẹlu awọn ara i u rẹ ti awọn ọmọ ẹgbẹ yi si pana ija na bi ọgan. Ekeji ni ti awọ ti o wa larin awọn Oloye marun kan ninu awọn Oloye Eko pẹlu Ologbe Ọba Adele keji ti o sọ wipe on rọ wọn loye.

A gbọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ yi ni nwọn ba awọn Oloye na pari ija na ti nwọn si fi di ẹniti o pada si iga Idunganran l ti ma ṣe ọsẹ iga, etutu ọsọsẹ ti awọn Oloye ma nṣe ni Isalẹ Eko.

Iru eyi wu wa, a si ki awọn Oloye inu ẹgbẹ n wipe nwọn ṣe pupọ, alajọbi ko ni jẹki o rẹ wọn, Ọlọrun Yoruba yio ma tọ wọn lọna ti nwọn yio fi ma gbe orilẹ awọn Yoruba ga, ajọṣe awọn ọmọ ẹgbẹ na ko ni bajẹ.

# Iwe Si Olotu

## Kini A Npe Ni Oselu?

Nkan ti nwọn npe ni iṣẹ dokita tabi oniṣegun ati iṣẹ agbẹjọro (lọya) ye wa pupọ, sugbọn nigbagbogbo ni a ngbọ ti nwọn ma nsọ wipe enia n ṣ e oṣelu. Ẹ jọwọ, olotu kinni nwọn npe ni oṣelu ati wipe b a w o ni enia ṣe le lọ si ẹkọ-oṣelu?

Mo ni aburo kan ti o ṣẹṣẹ pari iwe i ikọ nile iwe-giga sugbọn o ni i ṣ ẹ ti o wu on ṣe ni iṣẹ Oṣelu nitoripe o njẹ ki nwọn tete mọ oruko enia ka iri, o si njẹ ki enia dolowo ati ọlọla.

Ẹ jọwọ boya ẹ le sọ itumọ iṣe awọn oṣelu fun wa ati wipe ile iwe wo ni enia ti le kọ iṣẹ na ki o ja fafa ninu iṣẹ oṣelu ṣiṣe.

Ọlọtu mo dupẹ fun a y e ti ẹ g b a mi iwaju ni ẹ o ma lọ ọkọ ọba k o ni ṣa yin lẹsẹ.

Emi ni,
S. Ojo Idikan,
Ibadan

## AKIYESI:-

NIPA ALAYE IṢẸ OṢELU ẹnyin ọkawe wa, ti o ba di ọsẹ ti mbọ ẹ o gbọ alaye yi lati ọ w ọ ọkan ninu awọn ọjọgbọn wa ni kikun. Boya a si le ri ẹnit o le ṣe alaye tirẹ fun wa ninu yin, ti a ba ri iwe alaye rẹ na gba a o tẹẹ sinu iwe irohin yi ki awọn ọmọ wa le ri nkan ka, ki nwọn si ri kọgbọn lẹhin ọla.

—OLOTU

## Se Larubawa Ni Sardauna ?

A gbọ ti Olktu Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni Oke Ọya, Alhaji Ahmadu Bello sọ fun awọn ti o gba ni alejo ni Jerusalẹmu ni aipẹ yi wipe iran Larubawa ni on, ninu iran Anabi Mohamadu ni awọn obi on ti jade wa.

Oníkun ni mọ ika, bi na ba jẹbẹ nitoto, a jẹwipe awọn ara Oke Ọya ni awọn nṣe jika fun ara wọn, ti nwọn fi Ọmọ ilu ajoji ṣe aṣiwaju Ijọba wọn. O yẹ ki a yọ Ọlọla Ahmadu Bello kuro ninu ipo Olotu eto Ijọba ilu yi ki a fi ọmọ ilu Kano tabi Zaria ipo rẹ nitoripe ọmọ onilẹ ni o yẹ ki o ma ṣe ilẹ.

O yẹ ki a kiyesi ara nitoripe ioni kọ ni Alhaji Ahmadu Bello ti nsọ fun wa wipe ọmọ Larubawa ni on. O sọ ẹ ni ilu Ibadan nigbati nwọn nfi ile Mosalasi Jimọ tuntun lelẹ, o tun sọ ọ ni Sokoto. Ọrọ re o ẹnyin ara wa, ỌMỌ LRUBAWA NI SARNDANA KIṢE ARA WA.

Agege
Emi ni,
Layi Sarumi

# Eleti-Ofe D'araba

## Adajo Kotu Ibile

(O bọẹ loju ewe kẹta

Idi Ori ti awọn ri ki on mu iwe ori ọdun mẹwa ti on ti gba wa, O ni on ni ti ọdun mẹrin ko silẹ fun wọn sugbọn eyi ko tẹ wọn lọrun, nwọn si gbe on ju si u moto wọn wa si kotu. O ni ninu awọn ọlọpa si duro si kotu ti awọn ko ti fẹsun on kan on ni Lọya Agbaje wole de, ti on si bẹ ẹ wipe ki o gba on. Adajọ ni Lọya Agbaje ko wipe ki awọn saiọ tabi ki awọn da kotu na ru rara, ko ... si awọn adajọ kan ... ni kotu rara a fi akọwe kotu nkan pẹlu awọn akọwe meji ti nwọn joko ti i.

# Ijoba Si Ile Iwosan Si Oke Arin L'Eko

EKO — A gbọ wipe Ijọba Apapọse nṣe eto nla kan lọwọlọwọ lati kọ ile igbẹbi ati itọju awọn alaboyun pẹlu awọn alaisan si adugbo kọkan ni igboro Eko ati pe eto na yio jalẹ ki ọdun yi to pari. Ọrọ yi ni Dokita Adekoye Majẹkodunmi, Minista nipa eto ilera fun ijọba Apapọse sọ nigbati o lọ ṣe ẹyẹ kan nibi ṣiṣi ile itọju awọn alaisan titun ti nwọn ṣẹṣẹ kọ si ọja Oke Arin ni Opopo John ni Eko ninu ọsẹ yi.

Minista na tun fi han gbangba pe ọdun to kọja nikan ni wọn ṣẹṣẹ ṣe anfani ilọsiwaju si ile alaisan nla fun gbogbo enia ni Eko, sibẹ iru awọn anfani titun bayi ko ti to fun awọn enia kakiri.

Dokita Majẹkodunmi ni ihamọ ti i ma wa nigbagbogbo ni ile itọju awọn alaisan wọn jẹ ohun ti o nṣẹlẹ nipa ọ p ọ enia ti nwọn nwa fun itọju, o si jẹ nkan to jẹ ẹdun ọkan fun gbogbo awọn alaisan ati awọn Dokita ti o ntọju wọn pẹlu. Ogunlọgọ ni nwọn ti nwa dogo sile itọju awọn alaisan yi lati owurọ kutukutu sibẹsibẹ nwọn ko ni foju kan dokita.

Dokita Majẹkodunmi ni on ṣakiyesi pe ọpọlọpọ ninu awọn alaisan ati obinrin aboyun ti nwọn ma nwa gba egbogi ni nwọn nii ẹsẹ rin lati ọna jinjin wa si ile itọju awọn alaisan na, nwọn yio duro si titi lati owurọ titi di alẹ ki nwọn to ri egbogi gba. Wahala yi pọ pupọju o si yẹ ki atete wa ọna ti yio fi dinku,

O ni eto daradara bayi ni Ijọba ti pinnu lati kọ ile iwosan kọkan si adugbo kọkan pẹlu iṣẹ iwosan ni kikun ti yio si wa ni arọwọto onikaluku, ati pe ile iwosan na a ma wa ni sisi silẹ nigbakugba lojojumọ. Dokita Majẹkodunmi dupẹ lọwọ Olotu Ijọba Apapọse ẹniti o ṣe ọna fun kikọ ile iwosan na, papa nigbati gbogbogbo ti eto ilera nla yi kọkọ tan ka igboro Eko.




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le si sa nilaibilai, ko si wọn, o mọ daradara, owun lo si dara ju fun onje-sise, ina-titan ati lati ma fi yana Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI–OFE ti o kun fun irohin aladun losose.

**Akiyesi:** A nfẹ aṣoju ni awọn ilu wọnyi Ibadan, Abẹokuta, Ọyọ, Akurẹ, Iseyin, Awẹ Iwọ. Ilọrin, Ogbomọshọ ati Oshogbo. Ẹnikẹni ti o ba fẹ di aṣoju wa ni awọn ilu, ki oluwa kọwe si OLOTU, 28 Kosoko Street, Lagos.

## Okunrin Kan Ku Sile Ale Re

IDI ARABA—Ọpọ ọ ni ọrọ ko jantọ-janto ṣugbọn ọrọ iyawo wa di lanu-lanti ni Idi Araba ni Surulere ti adugbo ti awọn ara Eko mọ ni adugbo awọn ọmuti larin awọn ọkunrin meji ti nwọn pade ile obinrin kan ati ọkọ rẹ ni ọjọ kẹfa oṣu kẹfa ọdun yi ti nwọn si fija pẹẹta ti ọkan ninu wọn si ku bamu bamu fun lilu ti ọkọ obinrin na lu u.

Ọrọ yi ni nwọn mu wa si kotu kekere kan ni Yaba ni Ọjọ Aje to kọja, ẹniti o si sọrọ yi ni obinrin Fulani kan to nje Malama Fatima to ngbe Opopo Ishaga ni Surulere, nigbati o njẹri tako ọkọ rẹ atijọ to nje Ashahir Adum to si nṣe aṣọgba oru fun ile onisowo kan towa ni opopo Tafawa Balewa ni Surulere. Ọkunrin iyi ni ẹniti awọn ọlọpa mu fun pipa ọkunrin kan ti nwọn npe ni Mohamed Aruma Bagazird ni ọjọ kẹfa oṣu kẹfa ọdun yi lailetọ.

Malama Fatima sọ ni kotu pe ọkunrin ti o ku pẹlu ọrẹ rẹ kan wa ki on ni irọlẹ ọjọ kan ninu ile on, ṣugbọn lojiji ni ọkọ on atijọ ti o fi ọwọ ara rẹ kọ on silẹ wọ ẹ de o si bẹrẹsi fi igi ake lu awọn ọkunrin mejeji na. Nwọn ko ti pari ẹjọ na ni kotu bi nwọn ba ti pari rẹ si ẹ o ma gbọ.

# Benson Ko Lo Sepa-de Egbe Ni'llu Ibo

EKO...Oloye Theophilus Benson ti o jẹ igba keji baba salẹ ẹgbẹ Alakukọ ni a gbọ pe o kọ ko lọ si ibi ipade egbẹ igbimọ ijiroro ẹgbẹ Alakukọ ti wọn ṣe ni Umuahia ni irọlẹ ọjọ abamẹta to kọja.

Ijinlẹ irohin kan ti o han si igbimọ ẹgbẹ na ni nilu Umuahia ni ọjọ Ẹti to kọja nwọn ni ọkan ninu awọn ohun pataki ti nwọn yio sọrọ le lori ni ipa iwa ati iṣesi oloye Benson ọkanna ti nwọn ṣe asaro le lori ninu ipade kan ti nwọn ti ṣe ni ilu Ibini nin oṣu to kọja.

Ninu ipade ti nwọn ṣe ni Ibini, awọn igbimọ ajiroro fun eto iṣẹ ẹgbẹ na tun yan awọn igbimọ miran lati ṣe iwadi iṣesi oloye Benson eniti a gbọ pe o o lọ si ipade Ifidimulẹ Isowọpọ Enia dudu ni gbogbo ilẹ Afrika ti nwọn ṣe ni Kairo, ṣugbọ nigbati o pada si Eko lati Kairo o sọ fun awọn oniwe irohin pe on ko ni Farahan fun awọn igbimọ ti nwọn yan lati wadi iṣesi on ninu ẹgbẹ

Lọwọlọwọ ogunlọgọ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ni nwọn lo si Umuahia nibiti olotu ipinlẹ Ila Orun Dokita Okpara gbe nlo diẹ ninu aye isimi rẹ on ni o se alaga ipade ẹgbẹ na.

Oloye Okotie Eboh, Olotu eto inawo ijọba ati akapo ẹgbẹ Alakukọ sọ pe on ko ni ero lati fi ẹgbẹ alakukọ silẹ rara nitori ajumọse pẹlu ẹgbẹ Ọlọpẹ ṣugbọn tẹlẹ ri a gbọ pe o ti ngbero lati fi ẹgbẹ alakukọ silẹ ti o ba le ba ọlọpẹ se papọ O ni nkan ti awọn ọmọ ẹgbẹ on ba se ni on yio faramọ.

Ninu ọrọ rẹ si awọn oniwe irohin ni ilu Port Harcourt ni ọjọ Ẹti to kọja ninu irin ajo rẹ si Umuahia fun ipade ẹgbẹ o ni bi o tilẹ ti ni kọsẹkọsẹ pẹlu ẹgbẹ on ri ọpọlọpọ si pa ẹnu pọ si on dajudaju on nilati jọwọ ara on fun ipinnu ti nwọn ba ṣe le on lori.

## Awọn Ọlọpa Fe Gbogun Ti Danadana

KADUNA — Gẹgẹbi irohin kan ti a gbọ lati Kaduna ni ipinlẹ iha Ariwa wa lọsẹ yi, nwọn ni awọn ọlọpa Naijiria nda ọgbọn titun ti nwọn yio fi gbogun ti awọn ọlọṣa kakiri awọn oju ọna to je pataki ni ipinlẹ Ariwa nitori ole didani lọna to ngberu lojojumọ nibẹ.

Awọn ọlọpa diẹ ati ọga agba kan pẹlu mọto wọn ni nwọn yio lo kakiri oju ọna lati le mọ iyatọ larin adamọdi iti igi tabi okuta ti awọn ọlọṣa le gba di oju ọna moto lati ma fi yọ awọn arinrin ajo lẹnu.

Nigbati nwọn ṣe ikede ọrọ yi ninu ijoko ijiroro kan olori awọn ọlọpa agba agba to jẹ olubẹwo ati alakoso ile iṣẹ awọn ọlọpa fun iwadi nipa ọran dida ni ipinlẹ Ariwa, Ọgbẹni N.E. Inkster, o ni ọgbọn titun yi yio bẹrẹ ni ijio ni kete ti nwọn ba ti pari gbogbo eto ni pa rẹ tan.

O tun kilọ fun awọn ọlọṣa adanilọna na nipa nkan kan ti o pe ni "alejo tipatipa" ti awọn ọlọṣa na yio gba nibiti nwọn ba fi iti igi di oju ọna si.

Ọgbẹni Inkster, olubẹwo awọn ọlọpa on ṣakiyesi pe ole didani lọna ti wa pe gongo nisisiyi nilẹ yi eyiti o fi jẹ pe ko tun si ohun miran ti awọn ọlọpa le ṣe ju pe ki nwọn gba ọwọ ti o le pẹlu wọn lati le gbogun ti iru iwa jambu bayi.

E Ka Oro Adajọ Kotu Ibile

(loju ewe keta)

# Awọn Ode Ilu Ibadan Ko Rowo Osu Gba

IBADAN — A ri irohin kan gbọ laipe yi wipe ọdunrun awọn ọdẹ asọde ti awọn Ibadan ko aṣọ ijọba si lọrun ti kansulu ilu Ibadan gba ni oniṣẹ ni wọn ko ti ri owo oṣu fun wọn ni boya ni nwọn tilẹ ma san owo na fun loṣu yi tabi igbakugba lọjọ iwaju nitoripe Ijọba ko tọwọ si gbigba ti nwọn gba awọn ọdẹ na.

Idi ohun to fa nkan yi ni pe Minisita to wa fun eto ijọba ibilẹ kọ lati fọwọ si iye owo ti Kansulu na bu silẹ gẹgẹbi owo oṣu awọn enia wọnyi nwọn ni ọkẹ mejidinlogun le ẹgbẹrin pọnun o le mejidinlọgbọn (£36,828) ni gbogbo owo oṣu ti awọn ọdẹ na ni lati gba.

Lori ọrọ yi, awọn Kansilọ ilu Ibadan ti pinnu lati ran awọn ikọ lọ sọdọ Minisita ti o wa fun eto iṣẹ na ni lati bẹ ẹ ki o fọwọ si iwe owo na ki Kansulu ba le ri owo san fun awọn aṣọde na. Ojojumọ ni awọn ọdẹ yi nlọ joko si ile iṣẹ awọn kansilọ ni Oke Mapo nitoripe awọn onigbese wọn ko jẹki awọn sinmi nile.

# Eleti-Ofe Daraba



# United Church Plans In Nigeria 'Nearly Complete'

**LONDON** — Plans to unite Anglican; Methodist, and Presbyterian churches in Nigeria are nearing completion, the Archbishop of West Africa, the Most Rev: C. J. Patterson told our representative here recently.

In a statement on progress to united church in Nigeria, issued in London ba the Church Information Office, the Archbishop said the scheme of union owed much to South India; but following the advance of the Lambeth Conference, provided for an inaugural service at which there could be a unification of the ministry.

The Methodist and Presbyterian churches had each given the first of votes in favour at a year's interval, required of tem; Their second vote next January would complete their "expectdly affirmative decision'.

Of the eight Anglican dioceses in Nigeria, the seven concerned in the Church Union Committee had all vote overwhelmingly in the past few months in favour of the scheme and of entry inot union end of 1965.

## 20,000 Passengers By Hovercraft

LONDON — Two highspeed Hovercraft have carried have carried 20,000 passengers in eight weeks on a ferry service operating off Southern England

The ferry service, covering a five-mile trip between the holiday town of Southsea and the Isle of Wight, is being run by by Hover Transport Limited a recently-formed firm for being for hovercraft ferry services.

The machines are the SR. N2 and the smaller SR.N 5, both built by Westland Aircraft Limitted and disigned to travel at 70 knots.

The larger machine can carry a maximum of 70 passengers and the SR N 5, 20 passengers. For the ferry service, the service the SR N2 has been licensed to carry 50 and the SR- N 5 12.

# 34 Nigerians Win Commonwealth Scholarships

Thirty-four Nigerian students are among the recipients of 228 Commonwealth Scholarships tenable in Britain this year under the Commonwealth Scholarships and Fellowships Plan.

The students, who come from 28 Commonwealth countries, will begin their course of study at universities, and other institutions of higher learning, in September, for periods of one or two years.

The Commonwealth Scholarships and Fellowships Plan was conceived at the Commonwealth Trade and Economic Conferencea at Montreal in 1958 and the details were worked out at the first Commonwealth Education Conference held at Oxford England the following year

The Plan provides for 1,000 Commonwealth students to study at any one time in other Commonwealth coutries. Britain promised to provide 500 awards tenable at any one time; and this target was first reached last year and has been attained again this year. The awards cover the cost of fares, tuition fees and living expenses.

The Plan will come under review at the fourth Commonwealth Education Conference which opens in Ottawa reectly.




# Read and Advertise in ELETI—OFE

**Your Yoruba most exciting Weekly Newspaper.**

# Ilewe Aguda Amerika Ni Awon Ko Ko Omo Eniadudu

AMERIKA — Awọn alakoso ile-iwe ti ijọ Aguda ti awọn wa ni ilu Amẹrika ni awọn yio bẹre si gba awọn ọmọ alawọdudu si ile-iwe alakọbẹrẹ ti awọn ninu oṣu to mbọ yi laisi ikorira tabi laibikita fun ilu ti nwọn ti wa. Tẹtẹlẹ awọn Oyinbo alawọfunfun ilu Amẹrika ti gba enia dudu si ile-iwe wọn, ṣugbọn Ijọba ilu na ti fi ofin tuntun de wọn mọlẹ nisisiyi.

Padi kan ti o njẹ Richard O. Gerow Biṣọbu ijọ awọn aguda Ṣọọṣi Nachez Jackson ni o ṣe ikede lori ero titun yi o si tun ka iwe kan si eti igbọ gbogbo awọn ijọ ni akoko ti nwọn nṣe isin ọjọ isimi lọwọ ni ilu na o si ṣi gbogbo awọn ti nwọn jẹ ọmọ ijọ Aguda leti lati fi ẹmi igbagbọ ododo wọn han nipa gbigba ati sisowọpọ wọn lori mimu ki eto titun yi le jẹ ṣiṣe.

Alaiyapa sigbigba awọn ọmọ ilewe alakọbẹrẹ wọnyi ni o ṣe Konge pẹlu ero lati faramọ aṣẹ kan ti kotu ijọba Apapọṣe ilu Amẹrika ti ṣe lori wipe ẹnikẹni ko gbọdọ kọ lati gba awọn awọn alawọdudu si ilewe awọn alawọfunfun.

Adajọ agba ti ijọba apapọṣe ilu Mississippi kan si ti fọwọ si awọn eto kan lati pa awọn ile iwe alakọbẹrẹ kekeke pọ ninu oṣu to mbọ ati ṣise ẹkun fun ile iwe bayi ni ọdọdun lọjọ iwaju ninu awọn ilu to wa ni Jackson ati Biloxi, ati ni ilete ilu Leake ni Mississippi

Oloye Mr A: MAJEKODUNMI, ọkan ninu awọn aṣiwaju Ẹgbẹ Ọlọfin.



# Egbe Ajumosepo

(O bẹrẹ lo jue we kinni)

Siwaju ninu ọrọ rẹ, o ni aye wa fun ẹgbẹ ti o ba fẹ faramọ ẹgbẹ ti nwọn dasilẹ lẹhin ti nwọn ba ti ṣe aṣaro tan lori iwe ibere fun wiwọ ẹgbẹ awọn kan wa. ntoripe alafia awọn enia ilẹ Naijiria, ẹkunrẹrẹ ati igunrege idagba soke ilu, ifidimulẹ ijọba Apapọṣe, irẹpọ ati inu didun awọn enia ti ngbe inu rẹ jẹ ohun towa ni ọkan awọn ọmọ ẹgbẹ titun yi pipọ ju.

Larin ajọsọ ọrọ Oloye Akintọla ati awọn oniwe irohin kan awọn ti nwọn pejọ sibẹ bu sẹrin nigbati o dahun si ibere kan ti on iwe irohin kan bi nipa Oloye Benson, o dahun pe "Emi ko mọ Benson ti iwọ nwi. Tabi iwọ nsọrọ nipa Benson to nṣe ti ẹgbẹ Dẹmọ ninu ẹmi, ti o si ṣe ti Alakuko ni ti ara?"

Awọn ti nwọn ki Oloye Akintola pe o ku abọ ati awọn to tẹle n awọn Minista awọn alaga ati oludari igbimọ ile iṣẹ ijọba lẹhinna ni nwọn ba fi ibudo okọ ofurufu silẹ pada si igboro Ibadan larin ogunlọgọ awọn enia ti nwọn ti duro lati ii, ti nwọn si nfi oruko rẹ ati ti igbakeji rẹ damuso fun wipe Dẹmọ ni yio bori.

**Never**

refuse a trial run before you choose a car. Let the cars speak for themselves and be scrupulously critical when looking at different models. We are convinced (from long experience) that any Mercedes-Benz will pass such an examination with top marks. Please give us the opportunity of substantiating our claim.

**DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!**

MERCEDES-BENZ



**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28. Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor, (Olotu) Ola Onatade 15, Kosoko Street, Lagos, P O 467, Lagos,